# PREFACE.

## ỌRỌ AKIYESI.

Mo ṣe IWE KEKERE yi fun anfani awọn Onigbagbọ ati awọn ti nfẹ Ọlọrun. Ọpọlọpọ awọn Onigbagbọ ni ntọ awọn Alufa Imọle lọ lati lọ bẹ wọn lọwẹ ti ọna wọn ba daru ati ti wọn ba nwa Iṣẹ ati ohun miran eyiti nko fẹ sọ nihin.

Mo bẹ nyin, ẹnyin Onigbagbọ, pe ki ẹ ma ṣe tọ wọn lọ mọ nitorina ni mo ṣe ṣe *Iwe Adura Davidi* Iranṣẹ Ọlọrun yi, wipe bi DAVIDI ti mbere ohun gbogbo lọwọ Ọlọrun ti o msi nda a lohun, bẹ nã ni Iwe Adura yi ri. Ẹnikẹni ti o ba nka PSALM yi yio ri ojurere lọdọ Ọlọrun.

Ki o to mã ka Psalmu yi, o ni lati jẹwọ ẹṣẹ rẹ fun Ọlọrun ki o si jẹ ki ọkan rẹ mọ.

IHS

Nigbati a o ba mã ka Psalmu yi o ni lati kọju rẹ s. Zion tabi Ila-Orun.

Adura ti ã kọ gba ki a to mã lo Psalmu nã ni yi,

# ADURA.

Ọlọrun alãye, Ọlọrun gbogbo araiye, Ọlọrun gbogbo wa, gbọ ohun wa ninu anu rẹ ati ninu iyọnu rẹ, awa ti dẹṣẹ, awa ti ṣẹ si ọ, awa ti ṣe ohun ti ko dun mọ ninu aiye yi; nipa orukọ mimọ rẹ, Jehovah, dari gbogbo ẹṣẹ ti a ṣẹ si Ọ, lati igba ewe wa jiwa, awa bẹ ọ pẹlu Orukọ Rẹ mimọ, Oluwa awọn Oluwa, Ọlọrun awọn ọrun, Ọba mimọ, Ọba ti ki ku ti ki ṣa. Ọlọrun SABAOTH gbọ adura wa: Amin, SELAH.

Nipa igbẹkẹle Ọlọrun ati nipa gbigba Adura, ẹ o ri i wipe awọn Ọmọ-Ẹhin Kristi ṣe ọpọlọpọ Iṣẹ Iyanu gẹgẹ bi ti Oluwa wa; awa pãpã si le ṣe Iṣẹ Iyanu nipa orukọ Ọlọrun ati nipa gbigba Ọlọrun gbọ. Emi yio fi apẹrẹ Iṣẹ Iyanu Jesu Kristi Oluwa wa han gbogbo ẹnikẹni ti ko ba ṣe iyemeji, ti o si gbẹkẹle Oluwa Ọlọrun yio gbọ Ipe ati Adura rẹ.

## WO IṢẸ IYANU OLUWA WA.

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| Wo | ***Matt*** :— | ORI | 8 | ẸSẸ | 1 – 3 |
| ... | ... | | 8 | ... | 5-15 |
| ... | ... | | 8 | ... | 14 15 ati ori Ẹsẹ |
| ... | ... | | 8 | ... | 16 ati *Mark* ori ẹsẹ 1–32 |
| ... | ... | | 9 | ... | 2     2 - 3 |
| ... | ... | | 9 | ... | 20-22 |
| ... | ... | | 9 | ... | 27-30 |
| ... | ... | | 12 | ... | 10-13 |
| ... | ... | | 14 | .... | 35-36 |

## Iṣẹ Iyanu Oluwa Wa.

| | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Wo | *Matt* | Ọgi | 15 | Ẹsẹ | 22-28 | | Ori | Ẹsẹ |
| ... | ... | ... | 15 | ... | 30 | *Luke* | 7 | 22 |
| ... | ... | ... | 17 | ... | 14-21 | | | |
| ... | ... | ... | 9 | ... | 27-36 | | | |
| ... | ... | ... | 21 | ... | 14 | | | |
| Wo | *Luke* | ... | 4 | ... | 33 | | | |
| ... | ... | ... | 4 | ... | 40 | | | |
| ... | ... | ... | 7 | ... | 12-15 | | | |
| ... | ... | ... | 8 | ... | 2- 3 | | | |
| ... | ... | ... | 8 | ... | 27-33 | | | |
| ... | ... | ... | 13 | ... | 11-13 | | | |
| ... | *John* | ... | 4 | ... | 47 | | | |
| ... | ... | ... | 5 | ... | 2- 8 | | | |
| ... | ... | ... | 9 | ... | 1- 7 | | | |
| ... | *Mark* | ... | 8 | ... | 22-25 | | | |
| ... | *John* | ... | 9 | ... | 17-38 44 | | | |

Wo Iṣẹ Iyanu Awon Ọmọ Ẹhin Kristi Oluwa Wa.

Wo Iṣe awọn *Apostol*

| | Ori | Ẹsẹ |
|---|---|---|
| Wo Iṣe awọn *Apostile* | 3 | 2- 8 |
| | 5 | 14-16 |
| ... ... ... | 8 | 9-23 |
| | 9 | 33,34 36-41 |
| | 14 | 8-10 |
| | 19 | 11-12 |
| ... ... ... | 20 | 8-12 |
| | 27 | 8- 9 |

| | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| Wo | *Liviticus* | ... | ... | 26 | 14 | |
| ... | *Deuteronomy* | ... | ... | 28 | 15–22 | Estra |
| Wo | *Exodus* | ... | ... | 14 | 26 | |
| ... | *Ecleciates* | ... | ... | 38 | 9 | |
| Wo | *Psalm* | ... | ... | 107 | 17–20 | |

Ẹnyin onigbagbọ, nko wipe ẹ ṣe lo Egbogi, nitorina ni mo ṣe fihan nyin nihin ninu Iwe yi, Otitọ Adura a ma gba ti ọkan oluwa rẹ ba mọ ṣugbọn ewe mbẹ, nitori Ọlọrun ni o da ewe fun ilo enia lọ Wo woli Jeremaiah 46 verse 11

Moses papa fihàn wa wipe Ewe mbẹ nipa bibẹ Igi sinu omi ti o koro ni Marah t! o si sọ ọ di didun: wo *Exodus* ori xv Ẹsẹ 25. Ọpọlọpọ enia ni a wo nipa Omi wiwẹ tabi Agbo Isaiah ge igi ọpọtọ lati fi wo Ọba Hezekiah o si san

Tobiah wo baba rẹ san nipa fifi ọpọlọ mudunmudun ẹja pa oju baba rẹ o si san ṣugbọn maleka li o kọ ọ leyi, Christ pāpā mu Amọ̀ ati Itọ la oju afọju, nitorina Adura jẹ inkan pataki

*Note* :— Ẹnikẹni ti ko ba ye ki o kọ Iwe si Publisher ylo si la a ye e.